**Yamtara-Wala Journal of Arts, Management and Social Sciences (YaJAMSS)**

**Volume, 6** **Issue: 5** **June, 2025**

# ẸJỌ́ DÍDÁ NÍ KÓÒTÙ GẸ̀Ẹ́SÍ ÀTI KÓÒTÙ ÌBÍLẸ̀ NÍNÚ ÌWÉ ERÉ-ONÍTÀN *ÀÀRẸ ÀGÒ ARÍKÚYẸRÍ* ÀTI *ADÁKẸ́DÁJỌ́*: ÌPÈ FÚN ÀTÚNSẸ SÍ ÒFIN ÌDÁJỌ́ NÍ NAIJIRIA

**[1]Àjùwọ̀n, Samuel Adébáyọ̀ àti [2]Adékúnlé, Moses O. PhD.**
[1&2]Department of Linguistics and Nigerian Languages, Faculty of Arts Olabisi Onabanjo University Ago Iwoye Ogun State Nigeria

**Àsamọ̀**
Ohun tí iṣẹ́ yìí ṣàgbéyẹ̀wò ni ètò ìdájọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá àti ti ìdájọ́ ní ìlànà òfin Gẹ̀ẹ́sì ni orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Ìwé eré-onítàn Yorùbá méjì: *Ààrẹ Àgò Aríkúyẹ̀rí* tí ó dálé ìṣèdájọ́ ní ilé-ẹjọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá àti ìwé eré onítàn *Adákẹ́dájọ́* tí ó jẹ́ ìdájọ́ ni ìlànà ìdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì, pẹ̀lú àgbéyẹ̀wò èrò àwọn oníṣẹ́ ìwádìí mìíràn ni iṣẹ́ náà fi sàlàyé àmúyẹ àti ìsòro ètò ìdájọ́ kọ̀ọ̀kan. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé orílẹ̀ èdè yìí yàn ìdájọ́ ní ìlànà òfin Gẹ̀ẹ́sì lááyò tí kò sì káràmáásìkí àmúlò ìdájọ́ ní ìlànà ìbílẹ̀ mọ́. Látàrí ìdí èyí, ìwúrí láti ṣe iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí jẹ́ láti pe àkíyèsí pé àkùkọ ètò ìdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì kò ga jù ti ìlànà ìdájọ́ Yorùbá lọ̀. Ó fi Tíọ́rì Ìṣèdájọ́ Òdodo fún àwọn Ọ̀daràn, *(Criminal Justice Theory* ẹka rẹ̀, *Peacemaking Criminology Theory)* tí ó ń lọgbe ọ̀nà ìgbẹ́jọ́ mìíràn yàtọ̀ sí ìlànà kóòtù ìgbàlódé se ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ àtúpalẹ̀ iṣẹ́ náà. Ó di mímọ̀ ìwádìí yìí pé ìdájọ́ òtítọ́, òdodo, àìṣègbè tí kò ná ni lówó púpọ̀, ṣùgbọ́n tí ó mú kí àlàáfíà lẹ́yìn ìgbẹ́jọ́ láàrin olùpẹjọ́ àti olùjẹ́jọ́ wà ni ó jẹ àwọn ìpele ìdájọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá lógún ṣùgbọn tí èyí kò fi gbogbo ìgbà sí nínú ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹsì. Àwíjàrè ìwádìí yìí ni wí pé, ìdájọ́ ní ìlànà ìbílẹ̀ Yorùbá dára, ó si yẹ kí orílẹ̀ èdè yìí máa ṣàmúlò rẹ̀ ní fẹ̀gbẹ́-kẹ̀gbẹ́ nínú ètò ìdájọ́ ju bí ó ti ṣe wà báyìí lọ, kìí ṣe pé kí ó pa á tì. Iṣẹ́ náà dábàá ìṣàtúntò tí ó péye sí àgbékalẹ̀ ètò ìdájọ́, kí ó wá òpin sí rìbá fífún àti gbígbà nínú ètò ìdájọ́. Kí ìjọba pèṣe ẹ̀kúnwó àti kóríyá fún àwọn olóòtú ètò ìdájọ́ gbogbo ní ó lè mú kí àlàáfíà àti ìgbàgbọ́ bọ̀ sípò nínú ètò ìdájọ́.

Àkójọpọ̀ àwọn èdè ìperí nínú iṣẹ́ yìí: adájọ́, ìbílẹ̀, Gẹ̀ẹ́sì, kóòtù, olùpẹjọ́, olùjẹ́jọ́

## Ìfáàrà

Ọ̀kan lára ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó wọ́pọ̀ nínú iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ Yorùbá ni ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ ẹjọ́ dídá tàbí aáwọ̀ yíyanjú. Ohun tí ó sì máa ń jẹ̀ àwọn òǹkòwé lọ́kàn ni láti pe àkíyèsí sí alèébù tàbi ṣe kóríyá fún irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀. Ogunlọ́gọ̀ àwọn ìwé eré onítàn Yorùbá ní àkóónú àwọn ìtàn wọn sàfihàn èrò òǹkọ̀wé lórí ètò ìdájọ́, yálà ìdájọ́ ní ìlànà ìbílẹ̀ Yorùbá tàbí ti Gẹ̀ẹ́sì. Ninú irú àwọn ìwé eré onítàn báyìí ni a ti sa méji péré yàn fún àlàyé lórí ìbójúmu tàbi àì-bójúmu àwọn ìdájọ́ nínú àwọn eré onítàn náà, tí a si ṣàfihàn ìṣòro tí ó ń kojú ètò ìdájọ́ lóde òní. Àwọn iwé wọ̀nyìí ni *Ààrẹ Àgò Aríkúyẹ̀rí,(Ogunniran(1987)* àti *Adákẹ́dájọ́* tí Ọládélé (2007) ko.

## Ètò Ìdájọ́

Káàkiri àgbáyé ni ilé-ẹjọ́ ti jẹ́ ibùdó fún ìyanjú aáwọ̀ láàrin ẹni méjì tàbí láàrin àwọn ẹ̀dá alàáyè tí ó ń gbé nínú àwùjọ. Oríṣìí ni ìlànà àgbékalẹ̀ àwọn ìlé ẹjọ́. Ìdálúù ni ìṣèlú. Ìlànà òfin ìdájọ́ yàtọ̀ láti orílẹ̀ èdè kan dé òmínràn, ṣùgbọ́n iṣẹ́ ààbò àti àlàáfíà àwùjọ kan náà ló jẹ́ ète gbogbo ìlànà ìdájọ́. Àwọn olùṣàkóso tí ó ń yanjú aáwọ̀ ní ilé-ẹjọ́ ni à ń pè ní adájọ́, tí pàtàkì ojúṣe wọn gẹ́gẹ́ bi èrò Matson, nínú iṣẹ́ Obodoegbulam, Longe ati Nwoko (2019) jẹ́ láti wá ọ̀nà tí àlàáfíà, ìbáṣepọ̀ tó ti dòkú tàbí mú ìrankàn tí ó bá wàyé látàrí èdè àìyedè kúrò. Bákannáà, kí ìdájọ́ mú ìrora ẹni tí a sẹ̀ dínkù nípa dídá ẹ̀tọ́ rẹ̀ padà lọ́nà tí ó fi lè tẹ́ tọ̀tún-tòsì lọ́rùn. Ìlànà ìdájọ́ pẹ̀lú òfin ìbílẹ̀ Yorùbá ni ó tí wà ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá kí àwọn òyìnbó tó dé sí ilẹ̀ Nàìjíríà. Ìpele-ìpele ni ìlànà ìgbẹ́jọ́ tí a wí yìí wà. Ọwọ́ àwọn adarí, àgbààgbà, ọba, ìjòyè ìlú ni àṣẹ ẹjọ́ dídá wà. Àgbékalẹ̀ ètò ìdájọ́ náà kò dá ibùdó kankan ní gẹ́gẹ́ bí ilé ìdájọ́, tàbí kí ó ní akọ̀ṣẹ́-mọṣẹ́ nínú ìmọ̀ òfin gẹ́gẹ́ bí olùdájọ́ ju àwọn agbà ìlú lọ. Ètò ìdájọ́ yìí kò ní àkọsílẹ̀ òfin ìgbẹ́jọ́, bẹ́ẹ̀ kò ní ìkọ asòfin

tàbi ikọ̀ àwọn agbófinró bí ó ṣe wà nínú ìlànà ìdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì ti òde òní. Ṣùgbọ́n sá, àlàáfíà àti ìfọ̀kàn balẹ̀ wà nínú àwùjọ nítorí ìwà òtítọ́ tí àwọn olùdájọ́ fi máa ń yanjú aáwọ̀.

Àyípadà tí dé bá ètò ìṣèdájọ́ Nàìjíría látàrí dídé àwọn òyìnbó amúnişìn. Àwon òyìnbó Gẹ̀ẹ́sì yìí gba àṣẹ ìdájọ́ kúrò lọ́wọ́ àwọn aláṣẹ ènìyàn dúdú, wọn sì fi ìlànà ìṣèjọba ṣèdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì rọ́pò. Òfin orílẹ̀ èdè yìí, (2011) orí kínní abala kẹfa, ẹsẹ kínní tìtí dé kẹta ti gbé gbogbo agbára ìṣèdájọ́ lé ilé-ìdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì lọ́wọ́. Ilé-ẹjọ́ ní ìlànà òfin Gẹ̀ẹ́sì ni ó kù tí a le gbé ẹjọ́ gbígbọ́ lọ, àyàfi ẹjọ́ abẹ́lé lásán ni a lè gbọ́ ní ilé-ẹjọ́ ìbílẹ̀. Sunday, (2023) sọ díẹ̀ nípà ìdí tí òfin fi gbé ìdájọ́ ní ìlànà òfin Gẹ̀ẹ́sì lárugẹ pé:

> One of the reasons for the introduction of English law into Nigeria was,without doubt, the fact that the rules of customary law were inadequate to cope with the monetary economy and to regulate the large scale peaceful interpenetration of society arising from the establishment of British Administration
>
> (Ọ̀kan nínú àwọn ìdí tí a fi gbé òfin ìgbẹ́jọ́ Gẹ̀ẹ́sì kalẹ̀ nínú ìgbẹ́jọ́ ìgbàlódé ìlẹ̀ Nàìjíríà ni pé, ẹ̀rí àrídájú wà pé, àwọn òfin ìgbẹ́jọ́ ìbílẹ̀ kò kún ojú òṣùwọ̀n tó láti kápá àwọn ìṣòrò ẹjọ́ tí ó le máa ṣúyọ látàrí okòwò ìgbalódé ń mú dání, bákan ńaà, lílò òfin ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì yóò jẹ́ kí ó rọrùn fún àwọn aláṣẹ ìjọba Gẹ̀ẹ́sì láti ṣe ìjọba tuntun tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ gbékalẹ̀ láàrin àwọn ènìyàn orílẹ̀ èdè náà)

Pẹ̀lú ìlànà ìgbẹ́jọ́ Gẹ̀ẹ́sì tí orílẹ̀ èdè yìí yàn láàyò báyìí, àkíyèsí ni wí pé ìwà ìrẹ́nijẹ, ojúṣàájú, ègbè àti oríṣìíríṣìí ìwà ìbàjẹ́ tí kò ti wọ́pọ̀ tẹ́lẹ̀ nínú àwùjọ́ nígbà tí á ń dájọ́ ní ìlànà ìbílẹ̀ ti kún inú ètò ìdájọ́, tóbẹ̀ẹ̀ tí ko ṣe bẹ̀ẹ̀ sí ìgbẹ́kẹ̀lé àwọn ọmọ orílẹ̀ èdè yìí nínú ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ mọ́. Èyí ló fàá tí àwọn onkọwe lítíréṣọ àti àwọn oníṣẹ́ ìwádìí yòókú kí í fi yé lọgbe ìsòrò nínú ètò ìdájọ́, pẹ̀lú ìrètí àti ṣe àtúnṣe. Ògúnsínà, (2006) jẹ́rìí pé èrò àwọn oníṣẹ́ ọnà lítíréṣọ ni làtí sín ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ jẹ pẹ̀lú ète làtí kọ́ àwọn ènìyàn lẹ́kọ̀ọ́, dá ní lárayá, pàrọwà fún ìtẹ́síwájú tàbí pè fún àyípadà ohun tí kò bá d ára nínú àwùjọ. Bákan náà, ojúwòye Ọ̀kẹ́, tí Sunday (2023) tọ́ka sí sọ díẹ̀ nípa ìṣòro tí ó kojú ètò ìdájọ lórílẹ̀ èdè yìí, pàápàá ilé ìdájọ́ ní ilànà òfin Gẹ̀ẹ́sì. Ó jẹ́ kí a mọ̀ wí pé ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ yìí ní àbààwọ́n jíjẹ ọ̀daràn ní ìyà láijẹ́ pé ẹni tí ó fara gbá àkóbá ọ̀ràn tí ọ̀daràn dá rí ìtanràn gbà padà. Ó ní:

> (offenders are punished without making restitution; and emerging from prision, he is reconcilled neither to himself, his victim nor the society)
>
> Kí ilé-ẹjọ́ jẹ ọ̀daràn ní ìyà láìjẹ pé ó mú kí irú ọ̀daràn bẹ́ẹ̀ ṣe àtúnṣè tàbí san ààrọ̀ padà fún ẹni tí a jẹ̀bi rẹ̀. bí ọ̀daràn bẹ́ẹ̀ bá parí ìjẹníyà àtìmọ́lé tàn, ẹni tí a tìtórí rẹ̀ tií mọlé kò ní yọ́nú síi, tàbí báa ní àjọṣepọ̀ mọ́. Irú ọ̀daràn bẹ́ẹ̀ kò ní wúlò fún ara rẹ̀ mọ́, tàbí jẹ́ ìtẹwọ́gbà fún àwùjọ́ bákan náà.

Ó tún júwe ọ̀gangan ibi tí ìyàtọ̀ gbé wà láàrin ilé-ẹjọ́ Yorùbá sí tí Gẹ̀ẹ́sì pé ilé-ẹjọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń wá ọ̀nà ìdájọ́ tí ẹni tí ó jàre kò ṣe ní lọ láì rí ìtanràn tàbí ẹ̀tọ́ gbà lọ́wọ́ ọ̀daràn tí ó jẹ̀bi. Nítorí náà ni ó ṣe júwe ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá bí èyí tí ó máa ń fi ojú sun ìtùbí ìnùbí;

> ( .... pursuance of justice which does not reflect a situation where victory is given to one party but one that projects mutual and social benefit to all parties involved)
>
> (kì í sáábà tí sí ìfarahàn ìdájọ́ tí apá kan nínú àwọn ẹlẹ́jọ́ yóò ti jàre tán pátápátá. Dípò bẹ́ẹ̀, ó máa ń jẹ́ èyí tí yóò ṣe tọ̀tún-tò- sì lánfààní ni)

Bákan náà, ó pé ìdájọ́ ìbílẹ̀ ní ilé-ìdájọ́ 'dídùn lọṣàn yóò so' (legal Positivism), tí ó sì kà ilé ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì ní 'òfin borí' (legal realism), nítorí pé ó pọn dandan kí àwọn

adájọ́ ilé-ẹjọ́ náà tẹ̀lé gbogbo àlàkalẹ̀ òfin, láìsí àtinúdá nígbà mìíràn tí ẹjọ́ bá dojú rú. Èyí lè jẹ́ kí àwọn adájọ́ ilé-ẹjọ́ yìí má le ní ojú àánú tàbí ní agbára àforíjìn arúfin nígbà tí wọn bá rí àìlera irú arúfin bẹ̀ẹ̀. Síwájú síi, Olúkáyọ̀dé (1997) náà tọ́ka sí aléébù ìlànà ìgbẹ́jọ́ ìgbàlódé Gẹ̀ẹ́sì pé àwọn ilé-ẹjọ́ wọ̀nyìí máa ń sápamọ́ sí abẹ́ àkùdé tí ó wà nínú òfin ìgbẹ́jọ́ nípa fífa ìgbẹ́jọ́ nílẹ̀ tàbí lo ọgbọ́n àyínnìke mìíràn láti tú arúfin sílẹ̀ lálàáfíà nígbà tí wọn bá fẹ́ ṣègbè. Ó sọ ní pàtó pé:

> Under the modern legal system, a thief may be discharged and acquited on technical grounds, even if he was caught in the act, ...for this reasons some people will not bother to go to court, believing that they may not get 'justice'
>
> (Lábẹ́ ìlànà ìgbẹ́jọ́ ìgbàlódé, olè tí a gbá mú lọ́rùn ọwọ́ le bọ́ lọ́wọ́ ìjìyà ilé-ẹjọ́ bí ó bá mọ àyínìke òfin ..fún ìdí èyí, ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn tí ó yẹ kí wọ́n gbé ẹjọ́ lọ sí ilé ẹjọ́ kò wulẹ̀ ṣòpò ṣe bẹ́ẹ̀ mọ́ látàrí ìgbàgbọ́ pé àwọn kò ní rí ìdájọ́ òdodo gbà bọ)

Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ètò ìdájọ́ ní pé púpọ̀ nínú àwọn ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ tí a ń lò lọ́wọ́lọ́wọ́ ni kìí yanjú aáwọ̀ ní ìtùbí-ìnùbí. Wọn ní ìgbàgbọ́ pé tí ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì bá ti yanjú ẹjọ́ láàrin àwọn oníjà tán, àrankàn àti ìkùnsínú kìí tán nínú àwọn ẹlẹ́jọ́. Ìdí èyí ni wọn ṣe pòwe pé, a kí í ti kóòtù bọ̀ ká ṣọ̀rẹ́. Bí ẹjọ́ bá dé kóòtù Gẹ̀ẹ́sì nígbà mìíràn, ẹjọ́ àre lè di ẹjọ́ ẹ̀bi mọ́ ẹlẹ́jọ́ lọ́wọ́ bí àsìṣe bá wà nínú ẹjọ́ rírò. Nítorí èyí ni àwọn Yorùbá ṣe pòwe pé; ẹjọ́ láàkọ́, à kì í kọ́ ìjà. Kí olùpẹ̀jọ́ tàbí olùjẹ́jọ́ má ní ìmọ̀ kíkún nípà òfin ẹjọ́ rírò ní ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì ní ó le mú kí ọ̀daràn tí á mú fún ẹ̀ṣùn olè jíjà tàbí mú fún ẹ̀sùn ìfàdí obìnrín olóbìnrin ya járe ọ̀ràn, tí olùpẹjọ́ kò bá mọ ẹjọ́ gbé kalẹ̀ ní ọ̀nà tí ó tọ́. Bí ẹjọ́ bá dára, ṣùgbọ́n tí ẹlẹ́jọ́ kò bá mọ ẹjọ́ gbé kalẹ̀, tí kò sì gba akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ agbẹjọ́rò láti ṣe agbẹnuṣọ níwájú ilé-ẹjọ́, ó le jẹ̀bi bí alátakò rẹ̀ bá gbójú gbónù ni kóòtù.

**Òfin Ìdájọ́ àti àfojúsùn ẹjọ́ dídá**

Àwọn onímọ̀ gbà pé orísun òfin ìdájọ́ jẹ́ kókó ìdí abájọ àfojúsùn ìdájọ́ àwọn ilé-ẹjọ́ kọ̀ọ̀kan. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, Ògúnbọ̀wálé (2003) gbà pé Ẹlẹ́dàá ni ó kọ òfin sí ọkàn ọmọ Yorùbá láti mọ ohun tí ó tọ́ àti èyí tí kò tọ́. Nítorí náà, àṣà àti ìṣe ni púpọ̀ nínú àwọn òfin ìbílẹ̀ Yorùbá, kìí ṣe pé ìjọba kan ló gbé òfin kalẹ̀ tí gbogbo ènìyàn ń tẹ̀lé. Láti gbé àṣà àti ìgbàgbọ́ nínú gbígbé ní ìrẹ́pọ̀ ni ó máa ń jẹ́ àfojúsùn ìdájọ́ ìbílẹ̀. Okafor nínú Àìná (2015) náà jẹ́rìí wí pé orísun òfin ìbílẹ̀ Yorùbá àti Afíríkà lápapọ̀ wá láti ara ìrírí. ó ní;

> Laws are sourced from the African ontologial practice whereby both human and the devine laws are noted and collapsed with the intent of a peaceful and harmonious human existence in the society.
>
> (Láti ara àpapọ̀ ìrírí àwọn ènìyàn, àti ti àwọn òrìṣà, pàápàá láti ara àṣà àti ìṣe ni ilẹ̀ Adúláwọ̀ ni ó para pọ̀ di òfin, èyí ló mú kí àlàáfíà àti ìgbáyé-gbádùn wà nínú àwùjọ)

Ani, (2019), Adébáyọ̀ àti Akíntọ̀nà (2019) fara mọ́ àwọn èrò yìí. Wọ́n gbà pé àgbájọ èrò, ìmọ̀ tí ó wá láti inú àṣà ló parapọ̀ dí òfin ìdájọ́ àti ìṣèlú ilẹ̀ adúláwọ̀. Adébáyọ̀ àti Akíntọ̀nà (2019) fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé òfin ti ilé ìdájọ́ ìgbàlódé wá láti ọwọ́ àwọn aláṣẹ kàn. Wọ́n júwé òfin ile-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì gẹ́gẹ́ bí àṣẹ tí ikọ̀ alágbára kan gbé kalẹ̀ fún àwọn tí wọ́n ń jẹ gàba lé lórí, tí àwón wọnyìí sì gbọdọ̀ tẹ̀lé pẹ̀lú ipá.

> (a command...by sovereign to be obeyed by his/her subjects, and if not obeyed, certain punishment are attached to it).
>
> Àṣẹ ..tí àwọn olómìnira kan gbé kalẹ̀ fún àwọn tí wọn wà lábẹ́ akósó wọn, wọn kò gbọdọ̀ tàpà sí àwọn àṣẹ náà nítorí ìjìyà tì wà fún ṣíṣe bẹ́ẹ̀
>
> ,

Lérò wọn, kì í kúkú ṣe tìtorí ààbò àwùjọ nìkan nì àwọn òyìnbó tó mú ìlànà ìṣèdájọ́ ìgbàlóde ṣe gbé òfin ìdájọ́ kalẹ̀. Pàtàkì

àgbékalẹ̀ òfin wọn jẹ́ láti wá ọ̀nà tí àwọn ará ìlú kò ṣe ní yọ àwọn aláṣẹ̀ ìjọba lẹ́nu ni. Ohun ti gbólóhùn yìí ń tọ́ka sí ni wí pé òfin ìjọba ìgbàlódé jẹ́ àgbékalẹ̀ ìfẹ́ àwọn kan tí ó ń jẹ gàba lórí àwọn ará ìlú láti mú wọn ṣe ìfẹ́ inú àwọn aláṣẹ gẹ́gẹ́ bí olúwa àti amúnisìn ni. Ó jásí wí pé, òfin ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé kìí ṣe àjọmọ̀ gbogbo àwọn ará inú àwùjọ, àgbékalẹ̀ àwọn alágbára kan ni. Àwọn péréte kan ló gbé òfin kalẹ̀, tí gbogbo ènìyàn gbọ́dọ̀ pamọ́ nínú àwùjọ. Àwọn péréte tí wọ́n gbé òfin kalẹ̀ náà ni wọ́n ń pinnu ìjìyà fún gbogbo ẹni bá rú òfin ọ̀hún nínú àwùjọ. Agbára àti àṣẹ láti fi ìyà jẹ arúfin tún wà lọ́wọ́ àwọn kan náà. Nítorí tí àwọn ará àwùjọ kò lọ́wọ́ nípa bí òfin ṣe di gbígbé kalẹ̀, kíkọlu òfin bẹ́ẹ̀ kò le saláì má máa wáyé lóórè kóórè. Èyí si jẹ́ kí ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀ràn dídá wọ́pọ̀ nínú àwùjọ látàrí pé kìí ṣe gbogbo ènìyàn ni o mọ̀ nípa òfin. Bí ẹ̀sùn ọ̀ràn dídá bá ṣẹlẹ̀ láàrin ẹni méji, tí wọn sì kó ẹjọ́ dé kóòtù Gẹ̀ẹ́sì fún gbígbọ́, lọ́pọ̀ ìgbà nì àìní ìmọ̀ kíkún nípà òfin àwùjọ àti ìgbésẹ̀ ilé-ẹjọ́ máa ń ṣe àkóbá fún àwọn ẹlẹ́jọ́ tí wọn yòó jẹ̀bi. Kàyéfì ni wí pé, àìnímọ̀ nípa òfin tí ìjọba gbé kalẹ̀ kò ní pé kí arúfin bẹ́ẹ̀ má ṣe jìyà lábẹ́ òfin.

Oríṣìí ẹ̀jọ́ méji ló wà. Ẹjọ́ abẹ́lé. Ìyẹn ẹjọ́ pẹ́ẹ́pẹ̀ẹ̀pẹ́ láàrin ẹni méjì tí kìí ní ọwọ́ ìjọba nínú. Ẹjọ́ kejì ni àwọn ẹ̀sùn pàtàkì tí ó la òfò dúkíá àti òfò ẹ̀mí lọ. Ìjọba ìlú ni ó máa ń bá ọ̀daràn ṣe ẹjọ́ ilú ní ilé-ẹjọ́ tí yòò sì jẹ arúfin níyà. Nínú ìdájọ́ kídàájọ́, kí ẹlẹ́ṣẹ̀ ti jìyà ni àfojúsùn ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì. Sùgbọn Ọláọba (2002) jẹ́ kí á mọ̀ pé àfojúsùn ìdájọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá máa ń wo ọ̀tún àti òsì nígbà kan náà nínú ẹjọ́ dídá ni. Kì í ṣe pé kí ó jẹ ẹnìkàn níyà, kí ó dá ẹnìkejì láre tán pátápátá. Ìyẹn ni wí pé, ilé-ẹjọ́ yòó wá ẹ̀tọ́ olùpẹjọ́, yòó sì wá ẹ̀tọ́ olùjẹ́jọ́ bákan náà nípa 'ìwọ mú díẹ̀ wá, kí èmi náà ju díẹ̀ sílẹ̀. Èyí yàtọ̀ sí ojú àmúwòyé àfojúsùn ìdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì tí ó ped ní *'a winner takes all',* ìyẹn ni pé, ẹnìkan ni ó gbọ́dọ̀ jàre nínú ẹjọ́ rírò, kí ẹnìkejì sì jẹ̀bi. Ohun tí ó burú nínú àwọn ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì tí Ọláọba ń tọ́ka sí ni pé, ẹni tí ó jẹ̀bi ni yóò san gbogbo owó ìpẹjọ́ tí ẹni tó jàre ná. Bákan náà ni yóò san ìtanràn pé ó jẹ̀bi ẹjọ́ tí a pè é. Pẹ̀lú àfojúsùn pé ẹnikẹ́ni nínú olùpẹjọ́ àti olùjẹ́jọ́ tó bá jàre nínú ẹjọ́ dídá ni yóò gbà owó ìpẹjọ́ àti owó ìtanràn lọ́wọ́ ẹni tí ó bá jẹ̀bi. Gbogbo ipá ni olùjẹ́jọ́ àti olùpẹjọ́ máa ń ṣà láti rí pé àwọn jàre nínú ìgbẹ́jọ́. Èyí ló fà á ti wọ́n ṣe máa ń gba oríṣìíríṣìí ọ̀nà ẹ̀bùrú láti jáwé olúborí nínú ìgbẹ́jọ́. Kódà, àwọn olùjẹ́jọ́ tàbí olùpẹjọ́ le pàdí àpò iwà ìbàjẹ́ pọ̀ pẹ̀lú àwọn adájọ́ ilé-ẹjọ́ àti àwọn agbófinró, kí wọn lè rí ègbè nínú ìdájọ́. Irú ìgbésẹ̀ báyìí kì í mú kí ìkùnsínú tán lọ́kàn àwọn oníjà méjèèjì, tí àtubọ̀tán ìdájọ́ bẹ́ẹ̀ kì í si í mú ìrẹ́pọ̀ padà bọ̀ sí ààrin wọn bí ó ṣe ṣẹlẹ̀ nínú ìwé Àdákẹ́dájọ́ tí a ó gbé yẹ̀wò. Sunday, (2023) tí a ti ń tọ́kasí tẹ́lẹ̀ wá tẹ̀síwájú nípa ìgbàgbọ́ ìdájọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá pé:

> (In Yoruba judicial system, justice is not victory for one party in a game or battle, but socially beneficial, peaceful resolution of dispute that could otherwise constitute a threat to purity, well being and pros- perity of the entire community)
>
> Kì í ṣe bí a ṣe máa ń borí nínú eré ìdárayá, tàbí borí lójú ogun ni a ti ṣe máa ń borí nínú ìdájọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá, bí kò ṣe pé, tọ̀tún-tòsì ni yóò gbà nínú ìpín ìdá- jọ́, kí àlàáfíà le wá jọbà nínú ẹjọ́ tí kì bá àwuyewuye sílẹ̀, tàbí pagi dínà àlàáfíà ìlú.

Kò sí tàbí àwáwí pé ìlú kò fararọ nítorí àwọn ará ìlú kò ṣe bẹ́ẹ̀ ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú ìlànà ìdájọ́ tí ó yan kóòtù àti òfin ìdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì láàyò lórílẹ̀ èdè yìí. Ọ̀pọ̀ tí à fín ní ọ̀ràn ni kò ṣábà gbé ẹjọ́ lọ sí kóòtù ìjọba mọ́. Dípò bẹ́ẹ̀, àwọn ìlànà ìpẹ̀tù-ṣááwọ̀ mìíràn tí ó yàtọ̀ sí kóòtù Gẹ̀ẹ́sì tí òfin pa láṣẹ ni wọn a kó ẹjọ́ lọ nítorí ìdíwọ́ kan tàbí òmínràn. Nítorí àlébù àìsí ìdájọ́ òtítọ́ mọ́ jẹ́ kí ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀ràn dídá di púpọ̀ síi nínú àwùjọ tí púpọ̀ nínú àwọn arúfin sì ń lọ láì gba ìdájọ́. Àwọn tí a tẹ ẹ̀tọ́ wọn lójú mọ́lẹ̀ ṣùgbọ́n tí wọn kò ní agbára láti gbé ọ̀daràn lọ sí ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé a gbìyànjú láti dá ìjà ara wọn gbè nípa ìkọlura tí ó máa ń dá hílàhílo sílẹ̀ nínú àwùjọ nígbà tí ó jẹ́ wí pé ilé-ẹjọ́ ìbílẹ̀ tí ó wà ní àrọ́wọ́tó

ni òfin ìjoba ti dé. Ìbéérè tí a le bèèrè ni wí pé ṣé bẹ́ẹ̀ nì ìdájọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá ṣe burú to ni tí ìjọba ṣe yan ìdájọ́ ìlànà òfin Gẹ̀ẹ́sì ní ìpọ̀ṣìn?

**Tíọ́rì Ìṣèdájọ̀ Òdodo (Criminal Justice Theory)**

Tíọ́rì tí a dàpè ní Ìṣèdájọ̀ òdodo fún àwọn ọ̀daràn *(Criminal Justice Theory*) jẹ́ àkòrí orúkọ̀ àpapọ̀ tí a fún irin iṣẹ́ ìṣàtúpalẹ̀ ètò ìgbẹ́jọ́ lágbàáyé. Ojúṣe tíọ́rì yìí ní láti tanná ìmọ̀ ẹ̀kọ́ wo gbogbo àwọn ìgbẹ́sẹ̀ àti àtubọ̀tán ẹjọ́ dídá ní ìlànà ìgbẹ́jọ́ ìgbàlódé. Ó ń wo ipa tí ilé ìgbẹ́jọ́ ń kó, ojúṣe ọgbà ẹ̀wọ̀n àti ìhùwàsí àwùjọ sí ọ̀daràn lẹ́yín ìjìyà àtìmọlé arúfin. ẹka tíọ́rì yì*í* tí ó ṣe kókó nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí ni ẹka tí ó ń lọgbe ọ̀nà ìgbẹ́jọ́ mìíràn yàtọ̀ sí lílo kóòtù ìgbàlódé (*Peacemaking Criminology) Ì*wàásù ẹka yìí ni láti wá ọna mìíràn láti yanjú aáwọ̀ ní ìtùbí-ìnùbí yàtọ̀ sí kóòtù olófin Gẹ̀ẹ́sì. Àwọn agbátẹrú tíọ́rì yìí kó fẹ́ kí á gbé ẹjọ́ dé kóòtù onílànà òfin Gẹ̀ẹ́sì rárá níbi tí ìyanjú aáwọ̀ kìí tí i ṣe pẹ̀lẹ́ kùtù, àyàfi ìfiyàjẹni lábẹ́ òfin. Moloney, (2009) ọ̀kan nínú àwọn agbẹ́tẹ̀rù tíọ́rì yìí sọ̀rọ̀ nípa èròǹgbà tíọ́rì yìí pé;

> Peace making criminology is a perspective that suggests that alternative methods can be used to create peaceful solution to crime... the underlying goal of peace making criminology is to use a non violent approch to solving crime.
>
> (Tíórí yìí pè fún wíwá àlàáfìà àwọn ọ̀daràn pẹ̀lú ọ̀nà mìíràn tí àlàáfìà yóò fi bọ̀sípò láwùjọ láìjẹ́ pé a kó ẹjọ́ dé kóòtù ìgbẹ́jọ́ onílànà òfin ìgbàlódé rárá. ...ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ àfojúsùn tíọ́rì yìí ni láti lo ìlànà pẹ̀lẹ́-kùtù láti yanjú ẹjọ́ ọ̀daràn).

Àbá tí tíọ́rì yìí gbé kalẹ̀ fún àwùjọ ni láti tẹra mọ́ ìlànà ìlàjà ní ìtùbí-ìnùbí lọ́na tí àlàáfìà àti àjọṣepọ̀ tí ó gún régé yóò fi lè padà sáàrin àwọn tí a làjà fún lẹ́yìn ìpẹ̀tùsáàwọ̀ ju títẹra mọ́ ọ̀nà ìgbẹ́jọ́ nípa ìlo ìlànà òfin ní ilé-ẹjọ́ tí ó bá kùdùn láti fi ìyà jẹ ọ̀daràn lọ. Àbá yìí ni iṣẹ́ yìí lérò pé ó le mú kí á ti kóòtù bọ̀ ká ṣọ̀rẹ́. Bí ó bá wá rí bàyìí, ìlànà ìgbẹ́jọ́ bí ó ṣe wà ní ìlànà ìbílẹ̀ Yorùbá nígbà kan rí ni àfojúsùn tíọ́rì yìí. Ẹ jẹ́ kí á ṣàgbéyẹ̀wò èrò Ogunniran(1987) nínú ìwé eré onítàn *Àárẹ Àgò Aríkúyẹrí* ati Ọládélé(2007) *Adákẹ́dájọ́.*

**Kókó inú ìtàn *Àárẹ Àgò Aríkúyẹrí***

Ìtàn Àárẹ Àgò Aríkúyẹrí jẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó sẹ̀ sí ọ̀kan lára àwọn olóye, tí ó tún jẹ́ akọni ọmọ ogun Ìbàdàn nígbà tí Baṣọ̀run Ògúnmọ̀lá jẹ́ olórí ìjọba. Ògúnríndé Ajé ní orúkọ ọkùnrin yìí, oyè Àárẹ Àgò ni oyè tí ó jẹ. Gẹ́gẹ́ bí olóyè, tí ó tún jẹ́ akọni tí ó tún lówó lọ́wọ́, kò sí àní-àní pé ẹní-ọ̀wọ̀ gbá à ni nínú àwùjọ. Bí ó ṣe wọ́pọ̀ nínú àṣà Yorùbá, pàápàá láàrin àwọn tí wọ́n rí jájẹ láwùjọ, oníyàwó púpọ̀ ni Ajé. Ìyàwó mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó ní. Ajé yan ọ̀kan nínú àwọn ìyàwó rẹ̀ wọ̀nyìí láàyò tí ó sì fi ìfẹ́ tí ó ní sí hàn ní ọjọ́ tí ó ń ṣàjọ̀dún ìbọrí rẹ̀ nípa pé ó bá ààyò rẹ, Fátọ̀lá jó tí kò sì bá Aṣiyanbí àti Adépèlé jó lójú agbo ijó. Ìṣẹ̀lẹ̀ yìí fa ìtìjú fún àwọn ìyàwó méjèèjì lọ́jọ́ náà, tí àtubọ̀tán rẹ̀ dá owú jíjẹ sílẹ̀ láàrin àwọn ìyàwó mẹ́tẹ̀ẹ̀ta yìí. Láti kọ ẹ̀yìn Ajé sí Fátọ̀lá tí ó yàn láàyò, Aṣiyanbí tó jẹ́ ìyáálé nínú àwọn ìyàwó mẹ́tẹ̀ẹ̀ta gbé iwọ jẹ fún àwọn ọmọ ìyàwó kékeré, ìyẹn Adépèlé tí àwọn ọmọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta sì wọ́kú lójú ẹsẹ̀. Lọ́gán, Aṣiyanbí dúnràn ẹ̀sùn yí mọ́ Fátọ̀lá tí Aje tí ó jẹ́ bàbá àwọn ọmọ náà sì fi ìbínú pà Fátọ̀lá tí a dúnràn mọ́ láìjẹ́ pé ó ṣe ìwádìí kankan lọ síwájú. A kó ẹ̀sùn ìpànìyàn yìí dé ìgbẹjọ́ ní ààfin Basọ̀run Ògúnmọ̀lá fún ìdájọ́ ìbílẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí ète láti lè bọ́ lọ́wọ́ ìjìyà Ogunrnde Ajé bọ àwọn olóyè ilú nínú pẹ̀lú owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀, ìgbésẹ̀ tí ó jẹ́ kí ó dá ọ̀ràn kún ọ̀ràn níwájú Ògúnmọ̀lá adájọ́. Orísìí ẹjọ́ mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n dá nínú ìwé náà, ẹjọ́ ìpànìyàn, ìdúnrànmọ́ ni, àti ẹjọ́ àbẹ̀tẹ́lẹ̀ gbígbà.

**Kókó inú ìtàn *Adákẹ́dájọ́***

Àrẹ̀mú tí ó jẹ oyè Apèènà nínú Ẹgbẹ́ Ògbóni ni a pè lẹ́jọ́ ẹ̀sùn ìpànìyàn nínú ìwé náà. Ó gba owó lọ́wọ́ Kànmí tí ó jẹ́ ẹ̀gbọ́n ìyàwó rẹ̀ pé òun yóò bá àna òun yìí kó owó náà sí ilé ìfowópamọ́ títí tí pàṣípààrọ̀ owó tó ń lọ lọ́wọ́ nígbà náà yóò fi kásẹ̀ nílẹ̀. Lẹ́yìn oṣù kan tí ìpààrọ̀ owó ti kásẹ̀ nílẹ̀, Kànmí rán ni sí àna rẹ̀ Àrẹ̀mú pé àsìkò tì tó tí òun nílò owó òun,

ṣùgbọ́n Àrẹ̀mú kò dá owó náà padà. Ṣébí ojú àwo ni àwo fi í gbọbẹ̀, Kànmí gbérà láti Kàdúná tí ó ti ń ṣiṣẹ́ wá sílé láti lọ bá Àrẹ̀mú àna rẹ̀ nílé pé àsìkò tó tí òun fẹ́ gba owó. Àrẹ̀mú kò ṣe méní kò ṣe méjì, ó ní kí Kànmí dúró de òun nínú ilé kí òun fi lọ gba owó náà wá lọ́wọ́ ẹni tí òun kó owó sí, ṣùgbọ́n kò padà sí ilé títí ilẹ̀ ọjọ́ náà fi sú. Ìgbà tí Àrẹ̀mú kọ̀, tí kò dé mọ́, Kànmí ní láti dágbére fún àbúrò rẹ̀ tí ó jẹ́ ìyàwó Àrẹ̀mú pé òun ń lọ sí ilé, pẹ̀lú àdéhùn pé òun ń padà bọ̀ wá ní àárọ̀ ọjọ́ kejì láti wá gba owó òun lọ́wọ́ ọkọ rẹ̀. Ṣámọ̀-ṣamọ̀, àṣé Àrẹ̀mú kò lọ gba owó lọ́wọ́ ẹnìkankan! Dípò bẹ́ẹ̀, ń ṣe ni ó lọ dènà pẹ̀lú ìbọn lọ́wọ́ rẹ̀ de Kànmí tí ó jẹ̀ ní gbèṣè ni ojú ọ̀nà tí yóò gbà padà sí ilé. Ó fi òru bojú, ó sì yìnbọn pà á. Àṣírí ìpànìyàn yìí tú sí gbangba. Ìgbẹ́jọ sì bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹwu. Àrẹ̀mú rí ìdájọ́ ègbè gbà ní ilé ẹ̀jọ́ nítorí àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí ó fún àwọn olóòtú ètò idájọ́, ṣùgbọ́n àtubọ̀tán ìdájọ́ náà kò dárà nítorí pé àbúrò olóògbé gbé ìgbésẹ̀ ẹ̀san gbígbà, èyí tó ṣekú pa Àrẹ̀mú àti gbogbo àwọn tó lọ́wọ́ nínú ẹjọ́ dídá náà.

### Ìgbéléwọ̀n àmúyẹ àti àbùkù ìdájọ́ nínú Ìwé eré onítàn Ààrẹ Àgo Aríkúyẹrí àti Ìwé Adákẹ́dájọ́

Ẹ̀sùn ìpànìyàn ni wọ́n fi kan Ògúnrinde Ajé, Ààrẹ Àgò níwájú Basọ̀run Ògúnmọ̀la. Ohun àkọ́kọ́ tí á rí pé ó bójúmù nínú ìgbésẹ̀ ìdájọ́ ìbílẹ̀ Ààrẹ Àgò ni fífún ọ̀daràn láàyè àti oore ọ̀fẹ́ láti ro àròjàre ní ilé-ẹjọ́, àti níwájú adájọ́ bí ó ṣe wà nínú àṣà ìyanjú aáwọ̀ ni ilẹ̀ Yorùbá, àti nínú òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lágbàáyé *(Universal Declaration of Human Rights Article 10 (1948) right to a fair trial or due process,* àti *International Covention on civil and Political Rights (1966) Article 14(1)* tí wọ́n fi òté lé e pé;

> Everyone shall be entitled to a fair and public hearing by a competent, independent and impartial tribunal established by law
>
> (Gbogbo ẹni tí a pè lẹ́jọ́ ni wọ́n lẹ̀tọ̀ọ́ sí àǹfàání láti gbọ́ ti ẹnu wọn ní gbàgede, níwájú adájọ́ tí ó kún ojú òṣùnwọ̀n, adájọ́ tí ó ní òmìnira, tí kò ní ṣègbè nínú ìdájọ́, pàápàá tí a fi òfin gbé kalẹ̀)

Ó hàn gbangba nínú ìgbẹ́jọ́ náà pé ilé-ẹjọ́ lábẹ́ Basọ̀run Ògúnmọ̀lá fún Àárẹ Ògúnrìndé Ajé àti ìdílé rẹ̀ tí wọ́n fẹ̀sùn ìpànìyàn kàn ní àǹfààní ẹjọ́ rírò lábẹ́ òfin. Ilé-ẹjọ́ yìí kò dá afurasí náà lẹ́bi kí a tó gbọ́ ti ẹnu rẹ̀ níwájú àwọn onídàájọ́ rárá, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ọ̀ràn tí a pè é lẹ́jọ́ fún fojú hàn pé ọ̀daràn náà ti jẹ̀bi. Ṣíbẹ̀ ile-ẹjọ́ kò fi ọ̀daràn náà sínú òkùnkùn nípa ọ̀ràn tí a pè é lẹ́jọ́ lé lóri. Akọ̀wé ilé-ẹjọ́ kà ẹ̀sùn sí Ògúnrìndé Ajé lọ́rùn ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ẹ̀tọ́ (fair hearing) pé;

> Ìwọ Ògúǹndé Ajé, Àarẹ-Àgò Balógùn Ìbàdàn, o pa ìyàwó rẹ̀ Fátọ̀lá ní ìpa 'Ta-ni-'ó-mú-mì' nínú ilé rẹ̀, láì bìkítà fún ọlá-ńlá Baṣọ̀run Ògúnmọ̀lá, ẹnìkan ṣoṣo tí Olódùmarè fi ẹ̀mí gbogbo ènìyàn ìlú yìí àti ti amọ̀nà rẹ̀ lé l'ọ́wọ́, láti dási àti gbà. Ìwọ Ogúnndé, o ti tàpá s'ófin àt'àṣa ilú yìí,....... Bí mo bá parọ́ kí o já mi ní koro! (o.i.55)

Kókó àmúyẹ̀ ẹ̀ẹ̀kejì ni pé, gẹ́gẹ́ bí ẹ̀tọ́ tí ó bá ìlànà ìdájọ́ àgbáyé mu, ilé-ẹjọ́ yìí tún gba ìdúró fún Ajé tí a mú fún ọ̀ràn náà nípa pé, ó fún un ní òmìnira láti lọ sí ilé rẹ̀ kí ó sì fi ẹsẹ̀ ara rẹ̀ rìn wá sí ìgbẹ́jọ́ ní ọjọ́ kejì nígbà tí ìgbẹ́jọ́ ṣì ń lọ lọ́wọ́, dípò tí kì bá fi tì í mọ́lé gẹ́gẹ́ bí ọ̀daràn arúfin. Èyí jẹ́ ẹ̀tọ́ ọ̀daràn yìí, tí ilé-ẹjọ́ kò sì fi dù ún rárá. Nípa báyìí, ó fihàn wí pé ilé-ẹjọ́ yìí kó ògo ìlànà òfin ìgbẹ́jọ́ àgbàyé já, láti má ṣe rí afurasí tàbi àfẹ̀sùn kàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀daràn tí ó yẹ kí á jẹ ní ìyà síwájú ìdájọ́ gẹ́gẹ́ bí *article 11* àjọ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn àgbáyé ti wí pé;

> Everyone charged with a penal offense is presumed innocent untill proven guilty..... no one shall be held guilty of any penal offense on account of any act or ommission that did not constitute a penal offense at the time it was committed

(Gbogbo ẹni tí á bá pè lẹ́jọ́ tí a kò tí i rojọ́ kí á rí i pé ó jẹbi ní a kò gbọ́dọ̀ fojú òdaràn wò.... a kò gbọdọ̀ dá afẹ̀sùn kàn lẹ́bí lórí ẹjọ́ tí a kò tí í gbọ́ kí a sì gbéyẹ̀wò fínífíni)

Kò tán síbẹ̀, adájọ́ ilé-ẹjọ́ náà jẹ́ olóòótọ́ ènìyàn gẹ́gẹ́ bí àwùjọ ti tànmọ́-ọ́n pé adájọ́ gbọdọ̀ jẹ́. Ẹrí láti kín kókó yìí lẹ́yìn wá látàri pé ọ̀daràn yìí gbìyànjú láti fún adájọ́ ní owó rìbá kí ó le yí ìdájọ́ òdodo padà, ṣùgbọ́n ó ya ni lẹ́nu pé ó kọ owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ náà! Lẹ́yìn tí kò gba àbẹ̀tẹ́lẹ̀ lọ́wọ́ ọ̀daràn, kò tún jẹ́ kí àwọn tó gbà rìbá náà lọ lọ́fẹ̀ẹ́, dípò bẹ̀ẹ̀, ó jẹ wọ́n níyà ni. Eléyìí yẹ kí ó jẹ́ àwòkọ́ṣe rere fún gbogbo adájọ́ ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé òde-òni lápapọ̀. Àbẹ̀tẹ́lẹ̀ jẹ́ òkúta ìdènà sí ìdájọ́ òdodo ní irú ilé-ẹjọ́ yòówù tí kì báà jẹ́. Bí adájọ́ tàbí àwọn aláṣẹ ìgbẹ́jọ́ bá ti lè gba rìbá, wọn kì í tún le dájọ́ òdodo mọ́. Irú ìjókòó ìdájọ́ bẹ̀ẹ̀ sì léwù fún àlàáfíà àwùjọ. Bí àpẹẹrẹ, nígbà tí a kọ́kọ́ gbé ẹ̀sùn ìpàniyàn tí a fi kan Ògúnrìndé Ajé dé ìgbẹ́jọ́, tí kò tí i sí ìgbéṣẹ̀ àbẹ̀tẹ́lẹ̀ fífún ni, gbogbo àwọn olóyè ìlú ni wọ́n panupọ̀ dá à lẹ́bì lórí ọ̀ràn tí ó dá, tí wọn sì panupọ̀ pé ó yẹ kí ó jìyà ẹ̀ṣẹ̀. Balógun ní:

Á à! Ògúnrìndé! O dáràn tán, o tún dá'hun t'ó ju ọ̀ran lọ. Apàyàn ni ó
Baba! Ọwọ́ apàyàn ni ẹ jẹ́ á fi mú un. (o.i.59)
Kábíèsí, Ẹ-ẹ̀ mọ̀ pé gbogbo ará ìlú títí dé'lùú amọ̀nà l'ó ti gb'ọ̀rọ̀ yìí!
Gbogbo wọ́n sì ńwò wá b'á-a ti s'ẹ̀jọ́rẹ̀ sí. Kò gbọdọ̀ sè é gbé. (o.i.61)

Ifá àwọn ìjòyè wọ̀nyìí pohùndà lẹ́ṣẹ̀kẹṣẹ̀ tí Ògúnrìndé Ajé ọ̀daràn jàjà gbé ọ̀kẹ́ owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ fún wọn tán, èrò àti ìdájọ́ wọn yí padà lójú ẹsẹ̀. Ni wọ́n bá wòye pé jagunjagun àti olóyè ìlú ni ọ̀daràn náà jẹ́, àti pé, ó yẹ fún àforíji ẹ̀ṣẹ̀ tí ó dá. Balógun kan náà tí ó ti ń fapá jánú lákọ̀ọ́kọ́ pé ìdájọ́ ikú ló yẹ fún Ajé, ni ó wá pàdà gbé àbá ìdájọ́ ìdáríjì kalẹ̀ lórúkọ̀ gbogbo olóyè ìlú pé:

Káábíèsí, olúwa mi Iba, Nígbà t'a-a ránti ọjọ́, Orí gbogbo wa wu: Nítorí ọjọ́ l'ọjọ́, T'Ájé jagun nilé-e Kóro; Nítorí Ìbàdàn yìí L'o fi f'ọmọ bọ'lẹ̀ l'Ékìtì- Ẹfọ̀n. Gbogbo rẹ̀ l'a rántí, .. Ìdí rè-é, olúwa mi, Tí a fi pinnu pé k'a wo àtẹ̀yìnwá, K'a wo lààná Ajé, ka wo ti ohun ńla T'o ti gbe ṣe fún gbogbo wa, ... La ṣe foríkorí, L'a ṣe f'èròkèrò, L'a ṣe pinnu pé, K'a daríjin Ajé. (o.i. 83-84)

Èrò àwọn ìjòyè pé Ògúnrìndé Ajé ti forí la ikú kọjá fún ìmúdúró àlàáfíà ìlú Ìbàdàn lè jẹ́ òtítọ́ lápákan nítorí pé jagunjagun ìlú ni. Látàrí èyí, kókó tí iṣẹ́ ìwádìí yìí fẹ́ kí ó di mímọ̀ ní wí pé, gbígbé irú ẹ̀bẹ̀ báyìí kalẹ̀ ní irú àkókò yìí kì í ṣe òtítọ́ rárá, bíkòṣè pé iṣẹ́ owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí ọ̀daràn gbé fún wọn ni wọ́n ń ṣe. Iṣẹ́ ìwádìí yìí rí ọ̀nà tí àwọn ìjòyè yìí gbà gbé àwíjàre wọn kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ètè láti rù ìgbónárà ọkàn ilé-ẹjọ́ sókè fún àánú àìlẹ́tọ̀ọ́, kí ó wo àtẹ̀yìnwá, kí ó sì dárí ẹ̀ṣẹ̀ ji ọ̀daràn (an appeal to emotion and sentiment). Kò sí tàbí-ṣùgbọ́n pé òtítọ́ ni ó le gbé orílẹ̀ èdè lékè. Bí àwọn onídàájọ́ bá jẹ́ oní-rìbá, oníjẹkújẹ, wọ̀bìà, wọ̀-ǹ-bí-líkí bí àwọn ìjòyè yìí, kò lè sí ìdájọ́ òdodo rárá. Ìdùnnú àti àwòkọ́ṣe rere tí iṣẹ́ yìí fẹ́ tọ́ka sí ni wí pé, Baṣọ̀run Ògúnmọ̀lá kò gba rìbá lọ́wọ́ Ajé bí àwọn ìjòyè onídàájọ́ yòókù. Àìgba rìbá yìí ni ó sì fi le dá ẹjọ́ náà gẹ́gẹ́ bí òfin ìdájọ́ tì làá kalẹ̀ pé; ìdájọ́ ikú ni kí á dá fún ẹni bá ti jẹ̀bi ẹ̀sùn ìpàniyàn. Ògúnmọ̀lá kò wò pé olóyè, ọlọ́lá ni ọ̀daràn náà, tí ó fi dájọ́ ikú fún un gẹ́gẹ́ bí ẹ̀tọ́ pé; ẹni bá fi idà pa ẹnìyàn, idà ni kí a fi pa òun alára. Ó tún dájọ́ ikú bákan náà fún ìyàwó rẹ̀ Aṣiyanbí, tí òun náà lọ́wọ́ nínú ikú olóògbé náà. Àwòkọ́ṣè gbáà ni ìdájọ́ yìí.

Ní ìdàkejì ẹ̀wẹ̀, ìdájọ́ òdodo báyìí kò wáyé nínú irú ẹjọ́ ìpàniyàn kan náà tí wọ́n dá ní ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé nínú ìwé *Adákẹ́dájọ́* nítorí àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí ó wọ́pọ̀ ní ìlànà ìdájọ́ yìí. Olóòtú ìdájọ́ nínú eré onítàn Ààrẹ Àgò tí ṣe àpẹẹrẹ ìdájọ́ ìbílẹ̀ kọ owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí afẹ̀sùnkàn mú wá fún-un, èyí jẹ́ kí ó lè dájọ́ òdodo. Àwọn onígbọ̀wọ́ ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì nínú ìwé onítàn *Adákẹ́dájọ́* gbà owó rìbá tí Àrẹ̀mú náad fún wọn, nípà bẹ̀ẹ̀, wọ́n wá ọ̀nà àbáyọ fún Àrẹ̀mú. Èyí jẹ́ àléébù tí ó wọ́pọ̀ nínú ètò ìdájọ́ ìgbàlódé Gẹ̀ẹ́sì lórílẹ̀ èdè yìí, ṣùgbọ́n tí kò ti sí nígbà ti àwùjọ ń lo ètò ìdájọ́ ìbílẹ̀. Nínú ìwé eré onítàn náà, nígbà tí ìgbẹ́jọ́ kò

tètè wáyé ní ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì tí à gbé ẹjọ́ ọ̀daràn yìí lọ, ó jẹ́ kí àwọn onígbọ̀wọ́ Àrẹ̀mú tí ó ti wà ní àtìmọ́lé àwọn ọlọ́pàá rí oore ọ̀fẹ́ láti rí ààyè gbé owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ fún ilé-ẹjọ́ nípaṣẹ̀ àwọn ọlọ́pàá tí wọn jẹ́ asojú ìjọba ní ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì, wọn si sọ bí wọn ṣe fẹ́ kí ilé-ẹjọ́ dájọ́:

> A kò pé kí ẹ tú u sílẹ̀ pátápátá nítorí ariwo ará ìlú yóò pọ̀, ṣùgbọ́n ọgbọ́n àti ètè tí ẹ bá le lò láti ríi pé ọ̀rọ̀ kò ní yọrí sí ikú ni kí ẹ lò. (o.i.82)

Lóòótọ́, nígbà tí ẹjọ́ dé kóòtù, àwọn ọlọ́pàá ti bá Àrẹ̀mú yí àkọsílẹ̀ ẹ̀sùn ohun tí ó ṣẹlẹ̀ padà, wọ́n sọ pé ọ̀daràn náà kò dènà dé Kànmí, kò sì yìnbọn pà á bí wọ́n ṣe kọ́kọ́ rojọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìgbẹ́jọ́. Ẹjọ́ tí wọ́n gbé wá sí ilé-ẹjọ́ lẹ́yìn tí wọn ti gbàbẹ̀tẹ́ ni pé;

> A fi ẹ̀sùn kan Ọ̀gbẹ́ni Àrẹ̀mú Owólọjà pé ó rí òkú ènìyàn (tí àwọn ọlọ́pàá gbàgbọ́ pé olè yìnbọ́n pa lójú títì) ó dúró, ó wọ́ òkú náà sí ẹ̀gbẹ́ títì láì jẹ́ pé ó fi tó àwọn agbófinró létí. (o,i. 83-84)

À ó ṣàkíyèsí pé ẹ̀sùn tí ọlọ́pàá fi kan Àrẹ̀mú yàtọ̀ gédégédé ọ̀ràn tí ó dá. Ẹ̀sùn ọ̀hún kò sì le bí ẹ̀sùn ìpànìyàn rárá. Gẹ́gẹ́ bí alábàáṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú ilé-ẹjọ́, tí wọ́n sì mọ̀ nípa òfin ìgbẹ́jọ́, àwọn ọlọ́pàá mọ̀ dájú pé ìjìyà ẹ̀sùn tí àwọn fi kan afurasí yìí kò lè jású ikú fún un nígba tí kì í tí ṣe ẹ̀sùn ìpànìyàn ni. Wọn mọ̀ pé Àrẹ̀mú ọ̀daràn yìnbọn mọ́ olóògbé Kànmí ni. Ó sì tún fi àdá ṣá a ní ọrùn kí ó lè tètè kú gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ̀lẹ̀. Àwọn ọlọ́pàá rí ẹ̀rí pé fìlà tí ọ̀daràn dé bọ́ sí ara òkú tí ẹ̀jẹ̀ òkú sì mu fìlà náà dúndún. Fìlà Àrẹ̀mú tí wọn bá lára òkú ti júwe òsìkà. Ó sì jẹ́ ẹ̀rí àkọ́kọ́ tí wọn lò láti gbá a mú nígbà tí wọn fi ajá tí wọn kọ́ nípa òsìkà ẹ̀dá wáa rí. Níbìyìí ni ó sì tí jẹ́wọ́ òtítọ́ ẹ̀sùn náà pé òun ni òun pa Kànmí. Kò jẹ́ ìyàlẹ́nu nígbà tí akọ̀wé ilé-ẹjọ́ rojọ́ pé ọ̀daràn bá òkú lẹ́bàá títì ni, àtipé, nǹkan mìíràn ló fa ikú olóògbé nítorí àbẹ̀tẹ́lẹ̀.

Ìwádìí nínú iṣẹ́ yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé ó rọrùn fún àwọn ọlọ́pàá láti da ojú ẹjọ́ rú báyìí ní ilé-ẹjọ́ nítorí pé ìdílé Kànmí tí ó di olóògbé kò rí owó láti gba agbẹjọ́rò láti bá wọn ro ẹjọ́. Ó sì tún di mímọ̀ nínú ẹjọ́ náà pé ìsòrò pàtàkì ni owó agbẹ́jọ́rò tó pọ̀ jẹ́ nínú ètò ìdájọ́ Gẹ̀ẹ́sì tí kò sí nínú ìlànà ìgbẹ́jọ́ ìbílẹ̀ Yorùba. Àìrí owó láti san fún àgbẹjọ́ro ni kò jẹ́ kí wọn le lòó nínú ìgbẹ́jọ́. Sùgbọ́n àfẹ̀sùnkàn yìí rówó gbà agbẹjọ́rò. Agbẹjọ́rò tí ó gbà ṣiṣẹ́ owó rẹ̀ nípa pé ó bẹ̀bẹ̀ láti tako ẹ̀sùn tí àwọn ọlọ́pàá kà sí oníbàárà rẹ̀ lọ́rùn nínú àwíjàre rẹ̀ báyìí pé:

> Orí ẹ̀bẹ̀ náà ni mo sì wà fún ẹlẹ́jọ́ mi, àìmọ̀kan ló ṣe é, ìfẹ́ tí ó ní sí ìmọ́tótó ìlú ló mú kí ó ṣe bẹ́ẹ̀, àti lórí ẹ̀sùn kejì nípa àìfi tó ọlọ́pàá létí, àwọn kan dẹ́rùbá à pé bí ó bá lọ sọ ní àgọ́ Ọlọ́pàá wọ́n lè rò pé òun ló pa á ni ó ṣe sálọ tí fìlà sí bọ́ sílẹ̀. (o.i. 84)

Ó dájú pé adájọ́ tí ó dájọ́ mọ̀ pé àwọn ọlọ́pàá ti yí ẹ̀sùn ìpàniyàn tí ó yẹ kí wọn fi kàn ọ̀daràn padà bí ó ba ṣe pé ó ṣe ìwádìí lọ síwájú jù ẹjọ́ tí àwọn ọlọ́pàá tí ó jẹ́ àsojú ìjọbà rò mọ́ àfẹ̀sùnkàn lọ. Àmọ́, kò rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé, ó ṣe é ṣe kí àwọn ọlọ́pàá ti fún un nínú owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ tí ọ̀daràn san. Bákan náà, níwọ̀n ìgbà tí kò bá ti sí ẹ̀rí tí a bá gbékalẹ̀ ni iwájú adájọ́ ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì, kò bá ìlànà ilé-ẹjọ́ náà mú kí adájọ́ ilé-ẹjọ́ máa gba iṣẹ́ àgbẹjọ́rò ṣe, bí ó ṣe wà ní ìlànà ìgbẹ́jọ́ ìbílẹ̀ tí àwọn olùdájọ́ le bèèrè ìbéérè lọ́wọ́ ẹnikẹ́ní nínú àwọn ẹlẹ́jọ́. Bí ẹni tí a pè lẹ́jọ́ tàbí ẹni tí ó pe ni lẹ́jọ́ kò bá ti gba agbẹjọ́rò láti bá a rò ẹjọ́ níwájú ile-ẹjọ́ bíi ti àwọn òbí Kànmí yìí, ìwọ̀nba ni adájọ́ le gba iṣẹ́ agbẹjọ́rò ṣe nípa bíbèèrè ìbéérè ajá-ni-nírọ́ lọ́wọ́ èyíkéyìí olùpẹjọ́, tàbí olùjẹ́jọ́ kí ó má baà wá di pé ó ń gbè sí ẹ̀yìn ẹnikan. Ojúṣe àgbẹjọ́rò ni èyi. Ojúṣe adájọ́ ni pé ẹ̀rí tí ó bá wà níwájú rẹ̀ ní yóò gbé ìdájọ́ lé lórí. Ṣùgbọn, òfin ìdájọ́ ìbílẹ̀ fún adájọ́ ni àǹfààní lati bèèrè tàbí wádìí ohunkóhún tí a kò rò mọ́ ẹjọ́. Èyí ló fún Basọ̀run Ògúnmọ́lá ní ore-ọ̀fẹ́ láti lè wádìí lọ́wọ́ ìyáálé Ògúnrìndé Ajé, Asiyanbí pé òun fẹ́ mọ babaláwo ti ó dífa pe olóògbé Fátọ́lá ló fún àwọn ọmọ orogún rẹ̀ ní májèlé, ìwádìí tí ó mú kí òkòtó irọ́ Àsiyanbí já. Aìlera ìlànà ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì nìyìí. Ohun ni kò jẹ́ kí adájọ́ lè wádìí lọ títí nígbà tí ìdílé olóògbé Kànmi kò gba agbẹjọ́rò tí yòò járọ́ àwọn ọlọ́pàá. Nitorí náà, adájọ́ kò

ṣe rí ẹ̀rí àrídájú láti jẹ ọ̀daràn yìí níyà. Ó mú kí Àrẹ̀mú mú ọ̀ràn tí ó dá jẹ gbé. Ìjìyà ẹgbẹ̀rún kan náírà tàbí àtìmọ́lé osú mẹ́tà péré ni ilé-ẹjọ́ bù fún un lórí ẹ̀sùn tí wọn fi kàn-án pé ó wọ̀ òkú kúrò lójú ọ̀nà lái fi tó ìjọba léti. Ó ṣe ni láànú pé adájọ́ kó gba ìtanràn kankan fún ẹbí olóògbé Kànmí tí wọn pàdánú ọmọ wọn. Ìdájọ́ ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé yìí kò tọ̀nà rárá, ó sì tàbùkù ìdájọ́ ní ìlànà yìí. Ó júwe ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó kún fún àìṣedéédé, tí ó sì máa ń dá ìkùnsínú, àrakàn tàbí ọ̀tá sílẹ̀ lẹ́yìn ìdájọ́

Ìjọra àwọn ẹjọ́ méjèèjì (Àārẹ Àgò Aje àti Àrẹ̀mú) ni pé; ẹjọ́ ìpànìyàn ni ẹjọ́ méjèèjì. Wọ́n dá ọ̀kan ní ilé-ẹjọ́ ìbílẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n dá ẹjọ́ kejì ní ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé. Àwọn ọ̀daràn méjéèjì ni wọ́n gbìyànjú láti san owó àbẹ̀tẹ́lẹ̀ fún àwọn adájọ́. Ajé rán àwọn ẹmẹ̀wà ní iṣẹ́ àbẹ̀tẹ́lẹ̀ sí Baṣọ̀run Ògúnmọ́lá (adájọ́ ìbílẹ̀) ṣùgbọ́n ìyẹn kò gbà á, nítorí pé ìdájọ́ òdodo ni ó jẹ ilé-ẹjọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá lógún. Ó sì dá ẹjọ́ ikú fún ọ̀daràn ní ìbámu pẹ̀lú òfin. Àrẹ̀mú bákan náà rán irú iṣẹ́ àbẹ̀tẹ́lẹ̀ nípasẹ̀ ọ̀gá ọlọ́pàá Awóòsìkà (sí adájọ́ ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì). Ọ̀gá ọlọ́pàá gba rìbá lọ́wọ́ onígbọ̀wọ́ Àrẹ̀mú, wọ́n rojọ́ èké níwájú ilé-ẹjọ́. Ilé-ẹjọ́ sì dá ẹjọ́ lódì. Nípà bẹ́ẹ̀, Àrẹ̀mú mórí bọ́ nínú ẹ̀sùn tí ó yẹ kí ó jẹ̀bi ikú wí pé ó pa àna rẹ̀ Kànmí ní ọ̀nà àitọ́. Ó farahàn gbangba pe Aremú jẹ̀bi nítorí gbogbo ipele-ìpele ìgbẹ́jọ́ ìbílẹ̀ tí Àrẹ̀mú gbé ẹjọ́ náà dé kí ó tó dé ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì ni wọ́n ti dáa lẹ́bi. Fún àpẹẹrẹ, ìdájọ́ ní agbo ilé Àrẹ̀mú, lábẹ́ Baálé ilé àti gbogbo ìdílé rẹ̀ dá a lẹ́bi. Wọ́n sì fọwọ́ sí i kí ó jìyà ọ̀ràn tí ó dá. Ìdájọ́ wọn kò yàtọ̀ sí ti ìdájọ́ àwọn ẹgbẹ́ ògbóni ti Àrẹ̀mú ti jẹ́ olóyè. Àwọn náà dáà lẹ́bi bákan náà. Wọn kọ ọwọ́ ẹ̀bẹ̀ tí ó ra sí wọn láti ràn án lọ́wọ́ pé.

> Hà ẹ̀yin ọmọ ìyá mi Ajíbọ́lá. A ha lè pé alẹ́ yóò dára ká ba ààrọ̀ jẹ́? A ha le tìtorí pé a ṣawo kí á sì máa fọ̀ ayé lójú? A ń sawo lóòótọ, ṣùgbọ́n a kò gbọdọ̀ ṣawo kí a gbàgbé Olódùmarè Ọba Adákẹ́dájọ́. Èdùmàrè ń bẹ lókè tó ń wòṣe kóówá wa. Bí a bá tilẹ̀ ń ran ara wa lọ́wọ́, a ha le máa torí èyi hùwà ẹ̀wọ̀n. Awo tiwa kò wà fún ìbàyéjẹ. À ń fi awo tiwa táyé ṣe ni. *(o.i.75)*

Àgbájọ ẹgbẹ́ fi àáké kọ́rí pé, ìdájọ́ ìbílẹ̀ kò gbọdọ̀ fi igbá kan bọ̀kan nínú nínú ìdájọ́. Ìpele ìgbẹ́jọ́ yìí rí ẹ̀sún ìpànìyàn yìí gẹ́gẹ́ bí ohun tí ó burú, tí kò wu ètí gbọ́ rárá. Wọ́n bá ọ̀daràn wí. Ṣùgbọ́n àìní agbára lábẹ́ òfin láyé òde òni mọ́ ní ko jẹ́ kí àwọn ìpele idájọ́ wọ̀nyìí le jẹ ọ̀daràn náà níyà bí ó ti ṣe wà kí òyinbó tó gbé ìlànà ìdájọ́ tíwọn dé. Látàrí èyí ni wọn ṣe tàarí ẹjọ́ Àrẹ̀mú sí ilé-ẹjọ́ ìgbàlódé níbi tí o lágbárà láti gbọ́ gbogbo ẹjọ́ ìpànìyàn.

Ohun tí ẹ̀rí yìí fihàn ni pé ìlànà ìgbẹ́jọ́ ìbílẹ̀ kò ní àbààwọn, wọn kì í figbá kan bọ̀kan nínú, wọn kì í gbẹ́bi fáláre tàbí gbáre fẹ́lẹ́bi, ẹ̀kọ́ tí ó pè fún àwòkọ́ṣe. A rí i pé gbogbo àkitiyan Àrẹ̀mú láti lo ìlànà ìbílẹ̀ Yorùbá méjéèjì láti rí ìdájọ́ ègbè ni kò bọ́ sì i. Èyí yẹ kí ó jẹ́ àwòkọ́ṣe nínú ètò ìdájọ́ ìgbàlódé. Ó tún hàn dájú wí pé owó gegere tí ó nílò láti wá ẹ̀tọ́ ẹni lọ sí kóótù jẹ́ ìdíwọ́ fún ogunlọ́gọ̀. Èyí ni kìí jẹ́ kí ọ̀pọ̀ gbé dúkùú tí wọn bá ní lọ sí kóòtù. Ìdíwọ́ mìíràn ni wí pé ìgbẹ́jọ́ Gẹ̀ẹ́sì máa ń fàsìkò sòfò púpọ kí ó tó parí ẹjọ́ tí ó sì jẹ ìṣòro. Ní ìparí, írírí nínú àwùjọ jẹ́ kí á mọ̀ pé ètò ìgbẹ́jọ́ ìgbàlódé kún fún rìbá, àbẹ̀tẹ́lẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú àwọn ìwé eré onítàn méjèèjì. Ó sì pé fún àtúnṣe.

**Àgbálọgbábọ̀**

Lẹ́yìn àyẹ̀wò àwọn àpẹẹrẹ ìdájọ́ ní ìlànà méjèèjì nínú àwọn ìwé eré onítàn yìí fínnífíní, a ṣàkíyèsí pé kò sí ìlànà ìdájọ́ tí kò ní ibi tí ó kù sí. Ìdájọ́ ní ìlànà ìbílẹ̀ Yorùbá ní ìsòrò pé kò fàyè gbà lílo agbẹjọ́rò nínú ètò ìdájọ́ èyí tí kò bójúmu láyé òde òní tó. Bẹ́ẹ̀, kìí ṣe gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ nínú àwùjọ ni òfin wà fún bí Sunday (2023) ti lérò. Ṣùgbọ́n ṣá, gbogbo àwọn akùdé yìí kò sọ pé kí a pa ìdájọ́ ní ìlànà yìí tì pátápátá. Ara àṣà Yorùbá ni ìyanjú aáwọ̀ pẹ̀lú ìlànà àbáláyé. Ìdájọ́ ní ìlànà ìbílẹ̀ sì dárà bí ìjọbá bá lè túbọ̀ fàyè gba ìṣàmúlò rẹ̀ nínú ètò ìdájọ́.

Ẹ̀wẹ̀ ìdájọ́ ní ìlànà òfin Gẹ̀ẹ́sì kógo já nípa ílo akọ́ṣẹ́-mọṣẹ́ tó mọ̀ nípa òfin ìdájọ́, àti lílò agbẹjọ́rò, èyí tí kò sí nínú ètò ìdájọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá. Ṣíbẹ̀síbẹ̀ àmúyẹ yìí kò sọ wí pé kí ile ìdájọ́ yìí má ṣe kojú ìsòro. Ẹ̀rí wà pé bí lílo agbẹjọ́rò ti dára nínú ìlànà ìdájọ́ tó, owó ọ̀yà tí wọn ń gbà lọ́wọ́ oníbààrà jẹ́

ìṣòrò fún ọpọ̀ olùjẹ́jọ́ àti olùpẹjọ́. Ọ̀pọ̀ àwọn tí a tẹ ẹ̀tọ́ wọn lójú mọ́lẹ̀ ṣùgbọ́n tí wọn kò ní owó jaburata láti san fún agbẹjọ́rò kìí dábàá láti gbé ẹjọ́ dé ilé-ẹjọ́ rárá. Èyí sì pè fún àkíyèsí àti àtúnṣe. Ẹ̀wẹ̀, ìdíwọ́ mìíràn tí ó pè fún àtúnṣe ni ìfàsìkò sòfò ní ilé-ẹjọ́ Gẹ̀ẹ́sì. Bí ẹjọ́ bá pẹ́ nílẹ̀, àṣìṣe máa ń wáyé. Fífalẹ̀ tí ìgbẹ́jọ́ Àrẹ̀mú fàlẹ̀ kí ilé-ẹ̀jọ́ tóó gbọ́ ẹjọ́ ló fún Àrẹ̀mú ní ore-ọ̀fẹ́ kí ó rí àwọn olóòtú láti fún ní àbẹ̀tẹ́lẹ̀. Èyí nikan, sì kọ́, ìrírí nínú àwùjọ́ jẹ́ kí á mọ̀ pé ètò ìgbẹ́jọ́ kún fún rìbá àti àbẹ̀tẹ́lẹ̀ fún raarẹ̀. Àwọn ẹjọ́ méjèèjì tí a yẹ̀wò ni wọn ti gbé ìgbésẹ̀ àbẹ̀tẹ́lẹ̀ fífún àti gbígbà. Nítorí náà, iṣẹ́ yìí dábàá àtúnṣe sí ìlànà ìgbẹ́jọ́ nípa;

1. Kí ìjọba orílẹ̀ èdè yìí ṣe ìgbélárugẹ ètò ìdájọ́ ìbílẹ̀ kí ó lè jẹ́ lílò ní fẹ̀gbẹ́-kẹ̀gbẹ́ pẹ̀lú kóòtù ní ìlànà òfin Gẹ̀ẹ́sì tí òfin orílẹ̀ èdè yìí kàn ní pá. Nínú àṣà ni ètò ìdájọ́ ti jádé wá, àwọn ará àwùjọ si ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú síṣe bẹ́ẹ̀. Ṣùgbọ́n bí èyí yóò bá rí bẹ́ẹ̀, ìjọba gbọdọ̀ káràmáàṣìkí bí òfin ìdájọ́ ìbílẹ̀ tí kò sí ní àkọsílẹ̀ yóò ṣe di kíkọ̀ sílẹ̀ fún ìṣàmúlò.
2. Àdínkù gbọdọ̀ wà nínú owó púpọ̀ tí àwọn olùpẹjọ́ àti olùjẹ́jọ́ ń ná láti wá ìdájọ́ lórílẹ̀ èdè yìí. Èyí ni yóò fún ọ̀pọ̀ tí kìí lọ̀ sí ilé-ẹjọ́ látàrí owó gegere ti wọn kò ní ní ore-ọ̀fẹ́.
3. Ó yẹ kí àdínkù bá iye àkókò tí ìgbẹ́jọ́ ń gbà kí ilé-ẹjọ́ tó ṣèdájọ. Nítorí náà kí ìjọba fi gbèdéke àsìkò lélẹ̀ fún ìyanjú aáwọ̀
4. Orílẹ̀ èdè yìí gbọ́dọ̀ gbógun ti ríbà fífún ni àti gbígbà nínú ètò ìdájọ́ nípa àgbékalẹ̀ ìjìyà tó gbókan. Bákan náà kí ẹ̀kúnwó dé bá owó àwọn òsìsẹ́ ilé-ẹjọm gbogbo.

Bí èyí bá le di síṣe, ìdàgbàsókè àti ìgbàgbọ́ yóò túbọ̀ pọ̀ sí i nínú ètò ìdájọ́.

**Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí**

Adebayo, A., & Akintọna E. (2019). The Yoruba Philosophy of Law and the Challenges of Corruption in Nigeria. *African Journal of Humanities and Social Sciences (AJHSS, 1(1) 11-1.*

Aina, A. I. (2015). The Challenges of Accessing Justice in Comtemporary African Society: Lessons from Yoruba juristic practices. An online edition of *Al-Hikaat, 35,* 65-82. Downloaded 11 January, 2024, from https:www.researchgate.net.

Ani, C.C. (2019). Crime and Punishment in African Indigenous Law. Retrieved 23 April, 2024, from https://bit.ly/3cv6UY2 1-22

Federal Republic of Nigeria Official Gazette (2011). *Constitution of the Federal Republic of Nigeria as Amended*, Abuja: Government Press.

Moloney, J. (2009). Peace Making Criminology; undergraduate Review 5, Retrieved 11 April 2024 at https// vc. Bridgew.edu /undergrad-rev/vol 5/iss/16. Pp 78-83.

Obodoegbulam, A., Longe, K. and Nwoko, S. (2019). The Super Natural in Justice Delivery in Ogba, Ikwerre and Yoruba Traditions. *Tansian University Journal of Arts, Management and Social Sciences,* 6, 10-24.

Ògúnbọ̀wálé, P.O. (2003). *Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*. Ibadan: University Press

Ogunsina.B. (2006) *Sociology of the Yoruba Novel, An Introduction;* Ilorin, Integrity Publication

Ògúnníran, L. (1987). *Ààrẹ Àgò Aríkúyẹrí*. Lagos: Macmillan

Ọladele, S.(2007). *Adakẹdájọ́.* Akurẹ́: Lifesteps Publishers.

Ọlaọba, A.O. (2002). *Yorùbá Legal Culture*. Ibadan: F .O .B. Press

Olukayode, T. (1997). Traditional Versus Modern Judicial Practices: A Comparative Analysis of Dispute Resolution Systems among the South-West Yoruba of Nigeria. An unpublished paper presented at the International Association for Conflict Management, Gustav-Stresemann Institute V. Bonn, Germany. June 15th-June 18th 1997.

Oluwole, I. (1984). 'Conflict between Customary and Non-Customary Systems of Law: Preminimary Observations'. Retrieved 13 May, 2024, from http://www.nomos.elibrary. de/anbni.

Sunday, L. (2023). The Idea of Law in Yoruba Conceptual Scheme:An Interrogatory Discourse. *Nigerian Journal of Philosophical Studies* 2 (1) 77-84

United States of America(nd) *The sixth Amendment to the US Constitution, Glossary of legal terms-, U.S. Courts,* available at www.uscourts.gov

United Nations Organization, (1966) *Universal Declaration of Human rights* available @ http//.www.claiminghumanright. org